**AKIYESI PATAKI**

- Ni ti dandan, ẹnikẹni ti yoo ba fin kẹmika yii gbọdọ ṣe amulo awọn ohun idaabobo ara ẹni gẹgẹbi asọ idaabobo ti a maa n wọ le ori aṣọ, ibomu, ati digi idaabobo oju.
- O kere tan, a gbọdọ jinna si gbogbo ibudo ati ayika awọn ibiti a ba fin ni kẹmika apakokoro alaifojuri yii fun wakaati mẹjọ (8 hours) siwaju ki a to le pada si ibẹ tabi lati maa lo wọn.
- Ẹnikẹni ti o ba fin kẹmika yii gbọdọ fọ ọwọ rẹ mejeeji lẹsẹkẹsẹ lẹyin ti o ba ti fin kẹmika yii tan, bakannaa, ki o si tun wẹ iwẹ pẹlu omi ati ọṣẹ
- Ẹnikẹni ti yoo ba fin kẹmika yii, ko gbọdọ maa jẹ ounjẹ tabi mu omi ni akoko ti o ba n fin kẹmika yii lọwọ.
- A gbọdọ fi omi ati irepe asọ ti o bamọ nu awọn nkan eelo ti o ba wa ni agbegbe ibi ti a ba fin ni kẹmika yii siwaju ki a to le maa lo wọn.

**AWỌN OHUN TI A FI N PA KOKORO ALAIFOJURI TABI SE AFỌMỌ AWỌN OHUN AMULO TI AJỌ NAFUDAKI (NAFDAC) FI ỌWỌ SI, TI WỌN SI TUN BU ONTẸ LU**

| ORUKO AJUMỌ WỌN NI AWUJỌ | ORUKỌ KẸMIKA | AWỌN EROJA TI O ṢE GBOOGI NINU KẸMIKA |
|---|---|---|
| Hypo ™ | Sodium Hypochlorite | Sodium Hypochlorite 3.5% w/v |
| Jik™ | Sodium Hypochlorite | Sodium Hypochlorite |
| Dettol ™ | Chloroxylenol | Chloroxylenol BPC 4.8% w/v; oleum piniaromaticum 8.38% w/v; isopropyl alcohol 9.43% w/w; Sapo vegetable oil 5.60% w/w; saccharum ustumqs; aqual |
| Izal™ | Saponated cresol | 7% Tara Acid Phenol<br>2% Cresylic Creosote |
| Septol ™ | 5-chloro-2- hydroxydiphenyl methane | 2.3% pine oils and 1.1% 5 chloro-2-hydroxydiphenil methane |
| Savlon ™ | Chlorhexidine gluconate | Chlorhexidine gluconate (0.3 g), Cetrimide (3.0 g), n propyl alcohol as preservative (2.84% m/v) |

Fun alaye, ilana fifin ile ati ibugbe lati dẹkun tabi pipa awọn kokoro alaifojuri, ẹ kan si ikọ awọn akọṣẹmọṣẹ ti ipinle Ọyọ lori ẹrọ ibani sọrọ wọn yii: 08053506599; 08135882288. Tabi ki ẹ kan si wọn lori ẹrọ alatẹjiṣẹ itakun agbaye (email) yii: *covid-19containment@mail.oyostate.gov.ng/*

Gbogbo ọmọ ẹgbẹ ikọ ti o n gbogun ti titankale ajakale arun Korona (COVID-19) ti Ipinle Ọyọ dupẹ lọwọ Gomina wa Ọlọlajulọ Onimọ ẹrọ Oluseyi Makinde fun anfani ti wọn fun wa lati sin ilu ni ikapa yii.

**OYSG ©APRIL 2020**

# ILANA FINFIN ILE ATI IBUGBE LATI DẸKUN TITANKALẸ AJAKALẸ ARUN KORONA (COVID-19) NI IPINLẸ ỌYỌ



## ILANA FIFIN ILE ATI IBUGBE LATI DẸKUN TITANKALẸ AJAKALẸ ARUN KORONA (COVID-19) NI IPINLẸ ỌYỌ

Iwe ilewọ yii n ṣe alaye ilana ẹlẹsẹẹsẹ ti a o mulo lati fi ṣe afọmọ awọn gbọngan ọlọpọ eniyan ni awujọ wa kuro ni ọwọ ajakalẹ arun korona. Awọn gbọngan wọnyii ni gẹgẹ bi awọn ile ifowopamọsi, awọn ibudo itaja igbalode, awọn ile itaja elegboogi eebo, awọn ile ijọsin gẹgẹ bi Mọṣalaaṣi, Ṣọọṣi, awọn ile iwe jẹle osinmi, ile iwe alakọbẹrẹ, girama ati awọn ile ẹkọ giga, awọn ile ẹgbẹ ni adugbo, awọn ilegbe gbogbo ati bẹẹbẹlọ.

### AKIYESI PATAKI

O kere julọ, a gbudọ jinna si ibudo, ibugbe, ati awọn ayika gbogbo ibi ti a ba fin ni ogun apa kokoro alaifojuri fun wakati mejọ (8 hours) siwaju ki a to le pada si ibẹ tabi lati maa lo wọn.

### ILANA BI A ṢE LE PO KẸMIKA TI A O FI ṢE AFỌMỌ AYIKA ATI AWỌN OHUN IMULO WA

### IKE IFINKO KEKERE ONILITA MEJI (2 LITRES)



*A maa n lo eleyii lati fi fin awọn iho inu ile ati ibi kolofin, ẹnu ifa ilẹkun ati bẹẹbẹ lọ.*

- Bu ṣibi idakọmu meji ati abọ (2.5 tablespoons) Haipo (Hypochloride) pẹlu ṣibi kan eyikeyi ninu Aisaa (Izal), Ditọọli (Dettol), Sẹputọọlu (Septol), tabi Safuloọnu (Savlon).
- Rọ omi mọọ titi ti yoo fi pe lita meji (2 litres).

### IKE IFINKO ONILITA MẸJỌ (8 LITRES)

*A le lo eyi lati fi fin iyara ati awọn ile ibugbe*

- Bu ṣibi idakọmu mewaa ati abọ (10.5 tablespoons) Haipo (Hypochloride) pẹlu ṣibi merin ati abọ eyikeyi ninu Aisaa (Izal), Ditọọli (Dettol), Sẹputọọlu (Septol), tabi Safulọọnu (Savlon).
- Rọ omi mọọ titi ti yoo fi pe lita mejọ (8 litres).



### IKE IFINKO ALAPONSẸYIN ONILITA MẸRINDINLOGUN (16 LITRES)



A maa n lo eleyi lati fi fin awọn ibugbe gẹgẹ bi fulaati (flats) ati awọn ayika ti o ba fẹ tabi ti o ba gbooro.

Bu ṣibi idakọmu mọkanlelogun (21 tablespoons) Haipo (Hypochloride) pẹlu ṣibi mẹsan-an eyikeyi ninu Aisaa (Izal), Ditọọli (Dettol), Sẹputọọlu (Septol), tabi Safulọọnu (Savlon).

Rọ omi mọọ titi ti yoo fi pe lita mẹrindinlogun (16 litres).

### ṢIṢE AFỌMỌ AWỌN GBỌNGAN ỌLỌPỌ – ENIYAN

**AGBA ONILITA IRINWO (400 LITRES)**

- Bu lita marun-un ati abọ (5.3 litres) Haipo (Hypochloride) pẹlu lita meji ati ṣibi idakomu mẹwaa (2.1 litres) eyikeyi ninu Aisaa (Izal), Ditọọlu (Dettol), Sẹputọọlu (Septol), tabi Safuloọnu (Savlon).
- Da omi mọọ titi ti yoo fi pe irinwo lita (400 litres).



### AGBA TABI TANKI ẸLẸGBẸRUN KAN LITA (1,000)

- Bu lita mẹtala (13 litres) Haipo (Hypochloride) pẹlu lita marun-un ati abọ (5.5 litres) eyikeyi ninu Aisaa (Izal), Ditọọli (Dettol), Sẹputọọlu (Septol), tabi Safulọọnu (Savlon).
- Da omi mọọ titi ti yoo fi pe ẹgbẹrunkan lita (1,000 litres).

